Chief Secretary to the Government


# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. NO. 289 SATURDAY, NOVEMBER 3, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



7 NOV 1928


## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

N.B.—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, o si nje ki o ni aye wu arun mi silẹ.

A 20/4/

[signature]




LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
Dr. Earl S. Sloan

TO STOP
YOUR ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT

Sold by all Dealers.
Wholesale: Fassett & Johnson Ltd.
Clerkenwell Rd. London Eng.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA K[illegible]

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### ỌRỌ ẸJỌ ELEKO.

A gbọ pe Lọya Moore Agba ni Eleko yan lati ma ba ẹjọ on lọ.

### IWIN TABI ENIA !

Ni koipẹ yi ni irohin kan kan ni nipasẹ Ọlọpa kan ti o nṣode ni adugbo kan l' Eko nigbati o si di ajin bẹni a sọ pe o ri obinrin kan ti o nda rin lọ kemọkemọ: lọgan Ọpa Ọba yi ti sẹ wo pe nibo ni o nlọ ni idayi nigbati obinrin na si mbẹbẹ pe ki Ọpa Ọba na fi on silẹ ki on ma lọ ti Ọlọpa yi ko jẹ afi bi o ba on lọ si Tesọn lati lọ la idi ibiti on nlọ ni oruganjọ bayi ; bi obinrin yi si ti nlọ ti Ọlopa ntẹle bẹ ni a sọpe o gba Ọlọpa yi loju lojiji, ki Ọlọpa si to ṣiju pẹ bẹni obinrin na di ofo mọ loju : a sọpe aisan nla kọlu Ọlọpa yi lẹhin eyi.

## DUNIYAN—LABARI.

[ LATI ỌWỌ KEKERE-AWO. ]

### ỌJỌ IKẸDUN

Gẹgẹ bi atẹhinwa ọjọ kọkanla oṣu yi *November 11th* ni a ni lati kẹdun ni dede agogo mọkanla ti agba yio rọ nipa awọn ẹniti o gbọ 'gbẹ ni oju ogun, tabi ti o ba ogun ajakaiye na lọ, ṣugbọn ọjọ ọsẹ ni ọjọ yi bọ si lọtẹ yi nipa eyi nwọn o ta "pọpi" ni ọjọ Satide to mbọ.

### AWA-MỌTO.

A bẹ awọn awa-moto (*Motor Driver*) ki nwọn dakun ṣe ikilọ fun arawọn ani fun awọn miran, ọmọ aiyẹ ọbẹ ri ti o nwa ọbẹ si aiya ti nwọn ma nsaba fun moto lagbara lati le ma ya mọto miran ti o ba nlọ ni iwaju silẹ nigbati oju ba ni on nkan eyiti o mbọ lẹhin ; irufẹ ṣiṣe bayi ko dara arara ọpọlọpọ igba ni a ma nṣe akiyesi awọn owiwa wa wọnyi nigbati ogun ba gboju wọn tan, ṣugbọn o yẹ ki a mọ wipe nipa ṣiṣe bayi ma nran ewu lọwọ, ki awọn ti o nsaba wa mọto bẹ lọ jirẹdọ, barafo !

### "TOWN COUNCIL"

Yio dara pupọ julọ bi awọn Alabojuto ilu ba le ṣe akiyesi ode ti o mbẹ ni ojude ile Ọgbẹni Branco ni Massy Street, gẹgẹbi o ti jẹ ibiti o ma ngba omi laye lati rẹgun si i, nipa eyi ki nfun enia ni irọrun lati gba kọja, nigbamiran ti o mi na ba pọ nibẹ, bi ko ṣe ki oluwarẹ pa eti ibẹ tabi ki o gun ori irin ( Reluwe kokomaiko ) rin kọja—akiyesi pataki o !

### I N A O ... O !

Diẹ kinun lo ku ki ina kan ṣẹlẹ ni ile kan ti o mbẹ ni horo ibi ẹhinkunle ile Loya Abayọmi ni alẹ ọjọ Alamisi to kọja, eyi ti a nwi yi pẹ nwọn ti bo o mọlẹ, a gbọ wipe awọn Hausa kan ti o mbẹ ninu ile na lo fẹrẹ da hawu-hawu na silẹ—ankali o, Sọnnu aboki ! !

### NKAN NṢE NYIN DAN ?

Ẹnyin ti ẹ nlo idọti si arin ilu nipa ki ẹ ma ju igbọnsẹ si arin ita tabi ti ẹ gbe igba elepo ati owo ẹyọ melo kan sinu igba na ti ẹ ma ni ẹ nrubọ, o ri ẹlomiran lara, bi o ti lẹ jẹ wipe awọn gbalẹ-gbalẹ mbẹ fun titun ilu ṣe nkọ, a ha le ti itori eyi ma ṣe ọbun si arin ilu—kẹlẹkẹlẹ o !

### Y E P A R I P A !

Ni arin ọsẹ to kọja ni a gbọ wipe awọn ọmọ kekeke obinrin bi mẹrin kan kẹgbẹ lọ si eti 'ṣa ebute Idoluwo nigbati nwọn nkiri ọja gẹgẹbi iwa ipata ti nwọn ma nhu kiri, nwọn ko sinu ọkọ kan ti nwọn dẹtu rẹ si eti ebute na, a gbọ wipe lojiji ni ọkan ninu wọn tari ọkọ na si waju, nigbati ọkọ sun gere nwọn ni ki awọn da sọkalẹ ni ọkan ninu wọn ba fi bẹ si ori ṣago ni ṣago ba fi ṣẹ ẹsẹ rẹ bi ọsẹ ti nṣe oju, ẹse na fẹrẹ ja bọ ; iyoku di iregbe nwọn gbe ọmọ de na lọ si ti Dokita,

A ro wipe ọmọde yi sun awọn obi rẹ sinu wahala ni yẹn bẹ oja ni nwọn gbe le lori pe ki o lọ ta, ki o to ya bara lọ pade agbako tirẹ, dajudaju o yẹ ki ẹnyin ọmọ ti o nṣe ere ipata bayi kiri ode lọ fi eyi kọ 'gbọn, a si ro wipe nipa iru agbako baun awọn obi miran yio ṣe kilọkilọ fun awọn ọmọ wọn—ki Ọlọrun ṣe ẹsẹ na ni saki o.

## ẸRUN NFẸ YAN.

Lati bi ọsẹ meji yi ri õrun ti nmu yanyan, ni gbogbo ile si ti nmoru ti; a fi awọn onile-pẹtẹs ni nwọn yio ma gbadun aseko yi julọ nisisiy, nipa eyi o fi han wa wipe ojo arọkuro nlọ ni yẹn, ẹrun si nfẹ gba ode, ki Ọlọrun ṣe idakun sinu oru ti yio mu ni ilu ni ọdun yi.

## ẸGBẸ ANSARUD-DEEN KEKERE

Gẹgẹ bi iwe ikede, awọn Ẹgbẹ "Ansarud-Deen" kekere yio ṣe isin Ikore ni ọgba ile Iwe wọn ni Egerton Road, (Oke-arin) ni ojọ Jimọ ana ni dede agogo mẹfa; ni ọjọ Satide oni ni agogo mẹta ati ni agogo mẹsan abọ ọla ọsẹ nwọn yio ta oja Ikore wọn.

---

*(O bẹrẹ lati inu iwe ti ọsẹ to kọja).*

Sibẹ-sibẹ o fẹ ki awọn enia wa wo ohun ti wọn npe ni owo ṣe Ogbẹni yi ni store ni Ebute Idunmagbo ni Eko sibẹsibẹ o fi Eko silẹ lọ si Ile-Ifẹ— Bẹni nitori owo kan na yi ni, ninu ọdun ni ni gbogbo wa ma kọ gbọn ninu aita ọja yi, mo tun fẹ fun nyin ni ọkan si bi awọn oyinbo onişowo ilẹ yi ba ta ọja ninu "passbook" fun awọn onişowo wọn, ti wọn si ko ninu rẹ fun awọn akọwe wọn ni ṣabu, ti awọn kọral awọn oyinbo oniyun si lọ ba Agent wipe aṣọ bayi mo fẹ Bale bayi ninu rẹ mo si fẹ ki o din mi ni owo, agent yio gba ojẹgẹ yi fun oyinbo kọral, oyinbo kọral ko kọ erə ṣile kan lori igan kan, lẹhinna gbogbo enia yio ma ro lọ kiti-kiti lati lọ ra ti wọn, şugbọn wa sọ fun mi, ẹniti o ti ra ọja ti ẹ sinu Pass Book tabi akọwe to ti gba ti ẹ ṣabu, ko si wipe wọn ndin owo ọja ti ẹ ku, sọfun mi nibo lo ma ta ọja na si, iyẹn ko di gbese si lẹrun, Ẹyin ẹ tun ba mi wo ọran na wo, gbogbo ọja to wa ni Ṣabu Kọral ko si ti ilu wọn papa nibẹ bi ko ṣe ti ilu Gẹsi bawo ni oja tiwọn ṣe ndin ku, nitoripe ẹdin wo ni wọn ra, ere kekere ti to wọn, nipa bẹ o ṣoro fun ẹnikẹni lati ba wọn du tabi wọn fẹ fi ori gba ri pẹlu wọn. Nkan keji ko si ọrọ anikan jọpọn ni arin wọn, irẹpọ, isowo pọ wa ni arin wọn daradara nipa bẹ bi ikan ri ọja to pọ lati ra yio pin ekeji rẹ wọn asi ma ta ni iye kanna, ko si ija ni arin wọn, ki loṣe ti awa enia dudu ko le so ọwọ pọ, ọwọ talo fẹ so pọ ti David mọ ti Belo ni, tabi ọwọ Buraimọ mọ ti Muritalabi bawo ni irẹpọ nipa owo ni arin enia dudu yio ṣe duro dada. Ni asiko kan ti iṣẹ awọn Akọwe awo Esan Inspector of Produce wa ni abẹ Custom ọpọlọpọ awọn to nra Ekurọ, Cocoa, Epo tabi orişi-rişi nkan ọgbin gbogbo yi ni ẹ mọ idẹra ti ẹ ri, ni eyiti iṣẹ na bọ si ọwọ awọn oyinbo Agriculture ni lọlọ yi gbogbo yin ni ẹ mọ iyatọ to wa ninu rẹ, nitori pe gẹgẹ bi ofin ode isẹnyin, ẹniti owa ta ọja ni idọhọ yio ta, ẹniti ora lọwọ ero ni yio joko lati ma ṣe ayan rẹ ko le dara lẹhin to ba ṣa eyiti ko dara tan lẹhin na ni awọn awo ọja (Inspector of Produce) ati oyinbo wọn yio wa wo ọja na ki wọn to fi aṣẹ si fun wọn, lẹhin na ni oyinbo ti ẹniti o nra ọja yi fun yio to wa g'a lọwọ rẹ. Ẹyin enia wa tawo ni ọja na ko ṣe ni ẹniti ora ni ọhun, nipa sẹ eyi gbogbo yin ni ẹ o ma ri ka ninu iwe irohin ojojumọ wipe awọn akọwe to ma ra ọja fun awọn, awọn nfẹ owo tabi iwe ile lati fi duro ki wọn to le fun oluwa rẹ ni iṣẹ lati ṣe, ṣe oluwa rẹ papa yio fi owo tabi iwe ile rẹ ta tẹtẹ nipa irufẹ ọna bayi ẹlomiran le dahun wipe ṣe komişọn nkọ, awọ ko ka oju ilu, oju awọ papa ko pe iwọ ro wipe komişọn papa ko ti na ara rẹ, nipa bayi oyẹ wipe ki awọn enia wa ko ri si ki awọn oyinbo onişowo ma gba lọwọ awọn akọwe na ko to kan awọn Inspector nipa bayi awọn papa yio mọ wipe lala nlu—nkan to tun wa nipa ọja rira iyẹn nipe gbogbo awọn Niger Group iye kan na ni wọn nra ọja, awọn yẹn ni Niger Company, W. B. MacIver & Co, T. A. N, John Walkden & Co, tabi awọn miran ti a ko le ka miran wọn tan, bẹni iye ti Ollivant nra ni Tangalakis nra, bẹni Lagos Stores, African and Eastern, Miller Bros, Crombie Steedman, gbogbo awọn yẹn owọ kan na, aya fi John Holt & Co, ati C. W. S, la mọ awọn ti awọn yẹn pemọ mọ, nipa bayi aiye ti luja ara wọn, ninu rẹ na awọn ẹlomiran ngba Contract lọwọ awọn oyinbo wọn yi, to si nmu Motor lọ si ilu oke lati lọ ra, ẹlomiran ninu akọwe onişowo yi, yio fi Komişọn rẹ kun iye owo ti wọn ni ko fi ra oja nitoripe ko le ma ri oja ra, awọn oyinbo rẹ ko si ni fun ni owo miran kaka bẹ bo ba ra tan, didin ni ọja ma din si ni ọrun, gbogbo rẹ ama di ẹşilu, owo to fi duro a tan, iwe ile ade ọdọ onigbanjọ agogo ama dun gbongan, ko wa to aseko ti a ma ronu piwada ka mu ọran yi ni ekunkun dun, ka mọ ohun ti a ma fi si iwaju awọn oyinbo onişowo, nitori ko si ẹniti ole wa ta ọja to le da duro pẹ titi wipe ko joko ko ma ṣa gbogbo iwọn yẹn di iṣẹ Labourer rẹ bi bẹkọ awọn to wa ta ọja yi wọn a ba tiwon lọ, ere da ninu agbowo ka: Ẹ jẹ ki afi ọran ẹdun yi siwaju awọn alaşẹ ki wọn le yi ọua yi pada. Lakotan gbogbo yin lẹ o ri wipe ọpọlọpọ awọn oyinbo onişowo ni wọn nti Ṣabu awọn akọwe wọn ni oşoşu wipe ọja din, ẹ jọwọ ẹ ba wa fi ọran yi siwaju wọn, wipe ki wọn ma ka ọja ni oşu meji tabi oşu mẹta ki wọn si ma fun awọn akọwe wọn ni aiye ọsẹ meji ki ọjọ na toto ki wọn le fi gba owo to wa ni ode, nipa bẹ ko ni si ẹdin ọja, şe ki şe wipe gbogbo ọja wọn yi lo din şugbọn wọn ta si ode ni.

---

Gbogbo orilẹ ede ni gbogbo agbaiye lo mọ ohun ti wọn npe ni Ẹkọ kikọ, nipa ẹkọ kikọ ni enia ti nmọ ilaju, ibọwọ, oye, imọran, nipa ọna iṣẹ kişẹ ti enia nşe ni aiye, nipa ẹkọ ni a ti nmọ ohun to dara yatọ si eyi ti ko dara. Gbogbo orilẹ ede lo nfẹ ilọsiwaju llu nipa bẹ, eyi mu ẹkọ dani wipe

ẹnikẹni to ba ri aye rẹ ni lati kọ ẹkọ, osi ni lati kọ ọmọ rẹ ni ẹkọ to ja faufau nitori ẹkọ ni ogun ọmọ ni ẹhin ọla nipa bẹ ẹkọ yi jẹ ohun pataki pupọ fun ẹnikẹni. Gbogbo ẹyin agbalagba papa ni ẹ mọ dajudaju wipe ni asiko ti yin bi ẹ ba jade ni ile-iwe ọsan ẹ tun ni lati lọ si Lesson titi di oju alẹ, awọn imale wọn o lọ si ile kewu, won a fatia ni agogo mẹjọ wọn o lọ si Ile-iwe ni agogo mẹj -abọ tabi mẹsan to ba di ọsan wọn o lọ si Ile-kewu titi di agogo mẹta-abọ lẹhin na wọn o lọ si Lesson bakanna nipa bayi ẹkọ to jina haunhaun ni wọn nkọ, ni ọjọ isimi (Sunday) wọn o lọ si Sunday School ni ọsan eyi tun nfi ibẹru Ọlọrun si wọn lọkan nipa bẹ wọn njẹ ki won lọ siwaju nipa Bibeli wọn eyi tun fun wọn ni imọran ati oye ati lati bọwọ fun agba tabi fun ẹniti oju ọ lọ gbogbo iwọnyi si dara, awọn agbagba ijọhun ti wọn jẹ ọmọ mẹkunnu to jẹ wipe awọn obi wọn ko le ran wọn lọ si ile-iwe giga to si jẹ wipe iwe marun ti ile-iwe kekere ni wọn ka, njẹ mo bi yin awọn agbagba wọnyi ṣe fi ọwọ rọ sẹhin mọ loni nipa ẹkọ. Mo niran ni asiko kan to jẹ wipe bi C. M. S. Grammar School ti nyangan wipe awọn ni Olukọ ni, bẹni High School ni kilo ṣubu tẹ ohun, ako le sọ ti St. Gregory Grammar School igbana to jẹ wipe awọn oyinbo Aguda bi mẹfa ni wọn ngba ara wọn ni ira lojojumọ to jẹ wipe gbogbo ọmọ ile-ẹkọ ni lati mura de olukọni kankan nipa bẹ eyi nfun ọmọ ni ẹkọ to ja faufau, eyi si nmu owo awọn obi ko fu nọ nitori pe wọn nri apẹrẹ ibi ti wọn nnọ si, ko si ere pupọ ju ni asiko iṣẹ ni ile-iwe igbanọ gbogbo ere kere to wa fun ọmọ ile ẹkọ ni lati jẹ lẹhin ti ile-iwe ba pari tabi ni asiko *recess* ọmọ mi ko le ṣere nitori ẹkọ rẹ nitori pe tu nọ aṣiri kan wa nigbana ojojumọ Friday ni ọmọ ile-ẹkọ ni lati gba Card eyiti wọn ni lati fi han obi wọn bi wọn ti ṣe si ni ọsẹ na ati ipo ti wọn wa ni ile-ẹkọ bi ti ẹnikan ba fa sẹhin awọn obi rẹ wọn a fẹ mu lọ si ọdọ olukọ wipe bi ọmọde ti ṣe ni ọsẹ yi ko ye on nitori ko si iṣẹ ti wọn nfun ṣe nile, nipa bẹ bo ti ṣe si yi ko ye awọn, awọn olukọ wọn o ṣe ileri fun irufẹ obi bẹ, ọmọ na yio si yi pada si rere, ni asiko ti a nwi wọnyi, isinmi bi marun lo wa fun ọmọ ile-iwe, ni asiko Easter ọsẹ kan abọ ni—ni ọjọ ibi Ọba ọsẹ kan ninu ọsẹ kan yi wọn o ma lọ pa ilẹ mọ titi di ọjọ ti wọn ma to lọ si ọdan—ni oṣu June ti ojo ọsẹ meji ni asiko Christmas ile-iwe kekeke ọsẹ mẹrin ile-iwe giga ọsẹ mẹfa College oṣu meji, ni gbogbo isinmi wọn yi awọn ọmọ-ile iwe wọn nlọ si ọgba ile-iwe lọ ṣire nitori oti su wọn ṣugbọn loni nkọ aiye isinmi ni College oṣu mẹta ninu asiko ti wọn nkọ ẹkọ wọnyi siko eyiti wọn npe ni *Sport* iyẹn lati ṣe ere wa jan rẹrẹ ninu rẹ, nipa bẹ ọmọ to nlọ papa irọju ni wọn fi nlọ, ka tun wa lọ fun wọn ni oṣu mẹta isinmi njẹ awọn ọmọ yi yio kọ iwe mọ bayi. Awọn aba fẹni jẹ nkan laye wa ninn iwe irohin gẹgẹ bi oti tọ njẹ mo bere lọwọ irufẹ ẹni bẹ wipe irufẹ ẹkọ ti wọn kọ on papa ni yẹn, njẹ awọn obi rẹ wọn ran lọ si ọja Mushin pẹlu ẹsẹ bi, ẹnikan nda ni imọran wipe ka gbe ọran yi lọ si ọdọ awọn aṣoju wa mẹta ni Igbimọ Aṣofin ki wọn ba wa fi ọran yi si iwaju ijọba, ki wọn le gba tiwa ro nipa ọran tamutamu yi ṣugbọn awọn ti atẹ ilẹkẹ di atẹ ọrunla fun ni oju aiye wọn yi, to jẹ wipe afi-awa, afi-awa, ni wọn ngbe kiri ilu bi aṣa awọn ọmọ wa, wipe "Gbogbo rẹ to nothing ni" to jẹ wipe gbogbo fuja wọn yi to nothing ni, wọn ni awọn agbe lọ fun ara wọn, eyi ti ẹ gbe lọ siwaju Donald Cameron ni ijelo, mo bere lọwọ yin, ẹyin oloraye wọnyi, kini ẹ ba bọ wa yi o, enia le binu ori ko fi fila de idi, bi ọkọ yin ko de Igbimọ mọ, tani ẹ ma fi ikanra eyi mọ o Member, ọran to ṣe oju ilu ti ko fi ara sin ni eyi ti mo nwi yi, awọn ti wọn yan lọ si Igbimọ ẹgbẹ kan lo yan , wọn, wọn ko yan ara wọn, bi iwọ ba mọ wipe inu nbi ọ, mu ṣile meji rẹ lọ wọ ẹgbẹ, wọn o gba ẹsi ẹnu rẹ yio tẹlẹ ninu gbogbo ọran ilu, ohun kohun to ba ndun yin ni ilu, Ijọba yio gbohun yin, ṣugbọn ki ẹ wa di agbe ẹyin ba ẹbọ jẹ, eyi ku diẹ kia to, nitorina ẹ lọ pa imọran yin rẹ, bi ẹba ma ṣe ilu ẹ ṣe ni ọna totọ, ẹ ma gba ọna ẹburu wọ ile—ọran ilu ki ṣe ọran ẹnikan, nitori na bi ẹba fẹ ṣe ipade irufẹ eyi ni ọjọ miran ẹ pe ọkan ninu awọn aṣoju yin sibẹ ki ẹsi ran wọn si Ijọba nitori ọran isinmi ọmọ ile-ẹkọ fun oṣu mẹta eyi ṣe abuku bi ẹ ba fẹ kọ awọn ọmọ wa ni ẹkọ mọ, ẹ sọfun wa, nitori ile-iwe ti ko ba si ni abẹ ijọba, iyẹn wa ni ejiran, nitori oni iye ọmọ to ni lati ni ni abẹ rẹ, omiran awọn ọmọ ile iwe rẹ ko le ṣe idanwo Cambridge aya fi Preceptors to wa fun ẹnikẹni, iwọnyi ṣe abuku fun wa gẹgẹ bi ilu, o yẹ osi tọ fun ijọba ki wọn fun awọn ọmọ wa ni isinmi ọsẹ mẹfa tabi meje eyi to ninu ọdun kan, nitori pe ki enia ma san ogidinleje owo to to yẹu tan ki ọmọ na ma ni ẹkọ to dara to, iyẹn ṣe abuku. Bi ẹyin ba si fẹ lati mu ọran na lọ siwaju Ijọba ẹ mu lọ ni ọna to tọ ati eyi to yẹ, ẹniti o ba wa nibẹ lo nṣe bẹ, awọn Mọdakẹkẹ ni wọn nsọ nigbati wọn ṣe ape niti Balẹ ni Ibadan ti wọn npe Balogun ti wọn ni ko sọ ọrọ, ti iranṣẹ Balẹ bọ sode to ni Balogun Mọdakẹkẹ O. Balogun Mọdakẹkẹ si dahun wipe Ẹgan ni yeni, mo to Balogun Ibadan ṣe! Bo ba ma pe Balogun ko pe Balogun. Nipa bẹ ẹniti owa ni Igbimọ Aṣofin on ni aṣoju wa nipa bẹ ki ama pẹgan enia awọn kan ni wọn ti wa nibẹ ri loni nkọ lakuregbe Igbimọ ti gbe wọn ṣanlẹ, awọn aṣiwere miran wọn ṣe abinu ku iwe irohin wọn ani o gbọdọ mu iwe irohin yẹn de ile awọn, nipa iwa ba wọnyi, ale sọ pe iwa wọn nba wọn lẹru ni, bi ko ba si bẹ yẹn wọn le ma sa fun iwe kan lati ri, nigbati ko si ina ninu iwe na, ao duro nihin lọsẹ yi asi bẹ awọn aṣoju wa, ki wọn gba ọran yi yẹ wo, ki wọn si fi sinu ibere wọn wipe ki Ijọba din aye oṣu mẹta ku si ọsẹ mẹfa iyẹn pa pọju fun awọn ọmọ wa, wọn ko si ni ilu oyinbo nibi ti wọn ma ṣere gba,

ṣugbọn ni ilẹ yi awọn ọmọ ta pa pọju ẹgbẹ kẹgbẹ ni wọn ma ko larin oṣu mẹta na ti wọn fi ma gbagbe iwe wọn ti wọn si nifẹ lati kọ iwe mọ iyẹn nkọ O.

---

Inu mi dun pupọ lati ri ka ninu iwe irohin wipe Ogbẹni Daniel Kayọde ti "Accounts Branch Posts & Telegraphs" ni Eko, nwọn fun ni ipo igba-keji ọga agba iyẹn ni (A.C.C.—Assistant Chief Clerk) nkan to mu inu wa dun nipe ko si ẹnikẹni ti o gbọ nipa irufẹ ilọ si waju Ọgbẹni yi ti inu rẹ ko ni dun, gbẹrẹ lo ma maṣe, lo si ma ma rẹrin musẹ, Ọgbẹni yi jẹ aburo Lọya wa Victor Adedapọ Kayọde, bi a ba bere wipe tani Daniel fi iwa ki a yẹ enia si jọ tani awa darukọ aiya fi Victor bẹni Rosedale papa ntẹle Dan nipa bẹ gbogbo awọn ẹniti o mọ Dan ati awọn ẹniti o nba ṣiṣẹ ni nwọn nsọ wipe o nfi iṣẹ han wọn ko si ni igberaga si awọn ẹniti o nba ṣiṣẹ yala o wa ni abẹ rẹ ni tabi ni ọfisi kan na bakanna si ni si olukuluku, iwa rere Dan ni ile rẹ papa ti awọn enia nro iyin rẹ o kun wa loju, nigbati a ri ka ninu iwe irohin *Daily Times* ti ọjọ *Tuesday* ọsẹ yi, on lo mu wa kọ ohun ti awa nkọ nipa rẹ, awa ko ba ba iyawo rẹ yọ fun orire yi, ṣugbọn Dan ko ti ko ti obirn dani, ṣugbọn ẹma nlọ, afe nlọ o ni ki wọn ma ti da iho, ki lo tun ma mu ninu iho, o wa ni "first class" o ṣe kan, ni eyi ti o wa di A.C.C., nkọ majafara eyiti o ma ṣe ọ ni anfani ni Ọlọrun ma gbe ko ọ,—bi o ti nṣe bẹni ko ma ṣe, wa tun ri ipo to tun ma ju eyi lọ lagbara Ọlọrun, awọn to wa ni ẹhin rẹ wọn a ri ti won bakanna—Daniel gege rẹ ko niṣẹ, o ko ni lu igbadi Ọba.

---

Ẹnyin agbẹ, kini ohun ọgbin ti ri ni ọdun ni, ọpọlọpọ lo nsọ wipe obi ko tanna tobẹ, ati wipe irokuro ni ojo ọdun ni ro, njẹ a bere lọwọ ẹnyin agbẹ, eyi ha jẹ otitọ? Ọlọrun ma jẹ ko rl bẹ ni ọdun ni, nitori gbogbo ilu lo nkigbe aita ọja, njẹ awa dakẹ ni, ni ọsẹ bi mẹta ọhun mo kigbe ninu wosika mi si gbogbo ẹnyin onişẹ Ọlọrun wipe kẹ tẹwọ adura wipe ki oṣu November lọ di ipari ọdun yi, ma ri ti oṣu October fun wa, ki ọja ko ṣi, ki gbogbo nkan ko si ma ta wẹrẹwẹrẹ, ẹ jọwọ ẹ ma jẹ ko rẹ nyin, Ọlọrun yio gbọ adura nyin. Ohun keji ti ẹ ma gba adura fun pẹlu ohun ni ajaka-lẹ-arun to nja ni ode Eko yi, ki Ọlọrun ko bu ipa rẹ ku, ka ma si ri asiko yi anọ, ati wipe awọn ti nwọn gbe lọ si ile-alarun ni Ikoyi, ki Ọlọrun ko mu wọn bọ wa ba wa pẹlu alafia; ki Ọlọrun ko ma si ka wa kun awọn ti o lọ ninu ọdun ni. Ko si fi ara lile, iṣẹ anfani jinki wa ni oṣu meji to ku ninu ọdun ni. Amin.

---

Nipa ẹniti a ba yọ nipa ọjọ ibi, eyiti wọn ṣi orukọ rẹ tẹ sinu iwe yi mo fẹ torọ aforiji lọwọ orukọ na wipe Adolphin Vutade kiṣe bẹ "ADOLPHUS ELUTADE" ni. Ki orukọ yi ko fi ori jin wa, a ṣe yi ṣe ẹmi o.

Emi ni ti nyin nitoto,
ENIA KO DA BI ALLAH.

---

# NOTICE.

IN THE MATTER OF THE ESTATE OF

## AKINWUNMI AJOSE-ADEOGUN

(DECEASED).

*Pursuant to the Statute 22nd and 23rd Victoria Chapter 35, intituled "An Act to further amend the Law of Property and to relieve Trustees."*

Notice is hereby given that all creditors or other persons having claims or demands upon or against the estate of Akinwunmi Ajose-Adeogun late of 25, Agbojo Street, Idoluwo, Lagos, Nigeria, who died on the 9th day of July, 1919, intestate, and Letters of Administration of whose personal property were on the 9th day of August, 1928, granted by the Supreme Court of Nigeria to Akinola Ajose-Adeogun of 9, Ajose Court, Lagos aforesaid, are hereby required to send particulars of their debts, claims and demands in writing to me the undersigned, on or about the 30th day of November, 1928, after which day the Administrator will proceed to pay and distribute the assets of the said estate among the parties entitled thereto, having regard only to the claims of which he shall then have had notice and that he will not be liable for the assets or any part thereof, so distributed to any person or persons of whose debt, claim and demand he shall not then have had notice.

And all persons indebted to the said estate or holding any effects of the said deceased are hereby required to make immediate settlement or deliver the same to me.

Dated at Lagos this 15th day of October, 1228.

AKINOLA AJOSE-ADEOGUN,
*Administrator.*

# ILẸ IBO.

Ọna Motọ ja Enugu; bi enia ba fẹ wa si Eko fi aigba okun, yio de ibe; ọna Motọ wa lati Ẹnugu lọ de Onitsha, Onitsha de Benin, Benlin de Akurẹ, Akurẹ de Ilesha, Oshogbo; cyiti o ku, gbogbo wa, li o mọ ọ. Bẹ si ni bi o fẹ gba ọna Abakaliki; ilu na dara fun Motọ pupọ.

Atẹgun pọ, papa li alẹ; mo ro wipe nitori igbo ti ko si; bi ọdan li o fẹrẹ ri ko nmu enia li otutu arara.

Awọn ara ilu na, ọkan mi sọ fun mi wipe, boya awọn ni Ọlọrun da gbẹhin si aiye; nitori Adam papa, li ẹhin ti o jẹ eso igi tan, ti o ja ewe Ọpọtọ fi san Ibantẹ, fẹrẹ san ju ti awọn ọkunrin ilu yi lọ, ko ye mi iru ija ti nwọn mba aṣọ ja, ti nwọn ko nfẹ lo aṣọ; ọja kekere kan ṣa ni nwọn ma fi d'igo, ki a sa sọ wipe ihoho ni nwọn nwa; bi o ti wu ki otutu mu to, ko ṣe wọn ni nkan kan, tai ni awọn o ma lọ ko si ojuti, ko si faya *( fire. )*

Awọn obinrin wọn tilẹ sa i diẹ, awọn na ki nwọ aṣọ; ṣugbọn eyiti nwọn nsan mọ idi dabi Tobi; tiwọn san lọpọlọpọ li ẹgbẹ ti ọkunrin won. Nwọn si le bi'mọ pupọ, nigbati mo kọ nri wọn, ti ikun wọn tobi, mo ṣebi otutu ta'i arun li o wu wọn ni inu bẹ; mo wa bere wipe:—Awon ara ilu wa nyi ma ni arun l'ara o, kini ṣe ti ikun wọn wu bi ikun Dodo bayi? Nwọn ni ndao! arun kọ, oyun ni; mo wo titi, mo ni, anu Ọlọrun pọ! eyiti o jẹ wipe ni tiwa li ọhun, obinrin jaja l'oyun, kilo ti ma ṣe e, ki o to yi inu si otutu bayi? Awọn obinrin ara ilu na pọ.

Ohun kan pataki ti o wa ni ilu yi ni Edu inu ilẹ *( Coal mines, )* ẹniti o ba lọ wo ibẹ, yio kan sara si Oyinbo, yio si sọ wipe bi nwọn nta Edu kan ni pọnwun kan, o to bẹ; iho ilẹ ti nwọn nwa Edu yi, ori oke li o wa: bi enia ba bẹrẹ lati gun u, li aiṣe ani-ani, yio gba a to ọgbọn iṣẹju ki o to de oke. Li ọjọ ti mo lọ sibẹ, mo jẹjẹ wipe ko da mi loju bi mo tun jẹ lọ mọ, oke na ṣoro gun pupọ; ṣugbọn bẹ ni awọn ti nṣiṣẹ nibẹ ma ngun niyẹn o, "ati jẹun ọlọtọ ọro"

Ile ẹrọ kan wa lori oke na ti o nfẹ atẹgun si isalẹ, nijo ti a lọ sibẹ, nigbati a de ori oke, a sinmi diẹ awọn ti o nṣiṣẹ nibẹ wa tanna abẹla *( Candle )* a wọ inu iho ilẹ lọ, bi ọmode meji nṣire ṣa ni, a bẹrẹ si lọ, a nlọ, bi ẹniti o gbe'na dani ba jinna diẹ, enia ko tun ri'ran mọ, o di ki a ma a pe, ko duro; nwọn tẹ irin wọ inu ilẹ yi lo, *Wagon* si wa lori rẹ, ti o jẹ pe Edu ti nwọn ba wa, ninu rẹ ni nwọn ma ko si, ti nwọn o si ti i jade. Nibomiran ninu iho na, ko gba enia duro, a ni lati bẹrẹ dada, nitori bi ko ṣe bẹ e, enia o f'ori gba igi loke, omi nṣọn yaya, lapa kan nibẹ, ọna si wa yẹ ẹ yẹ ẹ, gẹgẹ bi amọna wa ti sọ, o ni ẹniti ko ba mo ọna yio wulẹ sọnu, yio si ku sibẹ, nitori ọna miran wa nibẹ ti nwọn ti pati, ti nwọn ko ṣiṣẹ nibẹ mọ, a rin titi fun iwọn mile mẹfa ki a to jade si odi keji, nigbati a jaja bọ si ode ni iha keji, mo f'ọpẹ fun Ọlọrun ti o mu mi jade l'alafia. Bi ilẹ ko ba ni p'ewura da, ko da mi l'oju bi mo le da'ba pe ngo lọ gbẹ edu ninu iho ilẹ, mo kan sara si awọn ti o nṣiṣẹ na, loju temi, owo girimọnyan lo yẹ ki nwọn ma san fun wọn, nitori nkankan kọ, ẹniti o ba nṣe iṣẹ na, mu ẹmi rẹ l'ọwọ, nko si ro pe a le ri ọmọ Yoruba kan ninu awọn ti o nṣiṣẹ na.

OWUYẸ.

---


## INA WỌLE OKUNKUN PARADA



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ mọ sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, NOVEMBER 3, 1928.

## ỌBA 'O KU ỌBA 'O JẸ.

Ẹnikẹni ti o ba ti nṣakiyesi ọrọ *Prince* Eṣugbayi Eleko lati igbati Ijọba ti wa lọ l' Eko lọ si ode Ọyọ ni yio ri pe otitọ ni ọrọ ti a kọ soke iwe yi, eyini ni pe "Ọba 'o ku Ọba 'o jẹ" ko le ṣe didun ilu kọkan ti a ba wa Ọba rẹ lọ lalai jẹ pe awọn ilu na sọ pe o ṣe ẹṣẹ nlanla kan; ero pupọ enia ninu awọn ti nwọn kẹhin si ọrọ Eleko ni nwọn ro pe, gẹgẹ bi Ijọba ti mu kuro ni ilu bayi ti nwọn si fi ẹlomiran rọpo rẹ laiku ẹkiri, inu ilu Eko yio yipada awọn enia yio si gbagbe ohun ti o ti kọja lọ: ṣugbọn bẹ ha ni bi? Dajudaju ko si ẹniti yio wipe bẹni, gẹgẹbi Eleko ko ti si ni arin wa loni sibẹsibẹ o tun mbẹ ni arin wa: ko si igbati awọn enia le fẹ lọ ki ni ibiti o wa loni ki nwọn ma ri lẹhin igbati nwọn ba ti tọrọ irufẹ aye bẹ lọwọ Oyinbo Oniṣẹ Ọba ti mbẹ nibẹ.

Nigbati iwe tabi waya jijare rẹ de ni ijele nibo ni a ko gbe gbọ irohin ayọ na: ọtọ ni ijo mukulu mukẹ ti o gba Eko kan laisọ ti ere ayọ ti ogọrọ awọn enia ṣe ni awọn ilu miran bi Onitsha, Port Harcourt, Ibadan, Ilọrin, Ọffa ati awọn ilu bẹbẹ lọ. Ohun pataki ti o si jẹ ki ilẹ gbogbo enia nibi gbogbo wa fun Eleko ko ju pe mimulọ ti a fi agbara Ijọba mulọ jẹ nkan ti ko jẹ didun inu ẹnikẹni ati ọkunrin ati obinrin afi awọn miran ti a ko mọ ohun ti Eleko na fi ṣe wọn

Nitotọ wiwa lọ tirẹ ki iṣe akọri ni *Nigeria* ẹlomiran le sọ pe ṣe bẹ ni nwọn nwa awon Ọba ilu miran lọ: esi wa ni pe bẹni; ati suke ko ṣẹhin lakuregbe itumọ rẹ ni pe wiwa ti Ijọba nwa awọn Ọba tabi Ijoye miran lọ ko ṣẹhin pe nwọn ṣẹ si ilu tabi enia wọn a ko si ti rika ninu Iwe-irohin kọkan ri pe Eleko su gbogbo Eko ati pe nitorina ni Ijọba ṣe ṣe ohun ti nwọn ṣe yi.

Boya ao ri awọn miran ti nwọn le ma sọ pe ṣe ebi ko pa bẹni orungbẹ ko gbẹ nibiti o wa lọhun: idahun wa si eyi tun ni pe tani a le wa lọ ni ṣaṣadidi kuro ni ile tabi ilu rẹ ti inu oluwarẹ le dun lati kuro lọdọ awọn enia rẹ pẹlu ipa

Tani ọrọ ti a sọ pe Eleko sọ lọpẹ yi ni Ọyọ nigbati a gbọ pe Lọya Zizer ati Ọgbẹni W. A. Dawodu lọ si ibẹ ko ṣe ni anu nigbati a gbọ pe o ba ọmọ rẹ okunrin kan wi pe ọmọ na fẹ ki on kn si Ọyọ ni.

Kakiri ni'a ngbọ igbe aifa ọja, ailọsiwaju ọ̀wọ̀ ati owo ti o ṣowọn ni 'lu njẹ lojiji ki Ilu gbọ pe Ijọba npete ati mu Eleko bọ ni ẹhin ọsẹ, nigbana ni ki ẹ wa woran bi owo yio ti ya si ilu nipa aimoye enia ti nwọn yio fẹ nawo nara, lati palẹmọ fun pipade rẹ. Lati igbati awọn ẹlomiran ti nfi enia rọpo Eleko lati igbana titi di oni ni kosi ẹniti o le sope odun mọ on ninu ẹgbagbeje awon agbarandun rẹ

A si mọ pe ojo adura ki ṣe alairọ lojojumọ pe ki Ẹni wa na ma ṣai pada wa ba olukuluku ni igboro ilẹ yi Ibi iyawo ni o, Ibi oku ni o, ko si ninu Orin ti awọn enia nkọ ti nwọn ki ṣalai ranti Eleko pe ki olufẹ ilu wa ma ṣaipada wa 'le ni alafia lati ba olukuluku ni alafia pẹlu.

Oju kan l' ada ni.

---

## *Olusakin's Column.*

OPEN LETTERS—PERTINENT AND IMPERTINENT.

To Lord and Lady Weymouth.

Dear Sir and Madam,—All sorts of people are worrying me because, at the recent baptism of your infant daughter, the godparents did not specifically, in her name "renounce the Devil and all his works." Not that I think it matters a scrap, but you know how particular some folks are. However, I hear that another unusual feature of the service was a prayer for the parents, and this innovation strikes me as an excellent one. Indeed, I have always thought christenings would be just as satisfactory if the baby appeared by proxy, so to speak, or if the ceremony were performed at home. Thank goodness, they can't burn me as a heretic nowadays.

JOHN BLUNT.

To the Rev. T. Rhondda Williams,
Chairman Congregational Union.

Reverend Sir,—What rubbish some of you parsons do talk, to be sure! And then you wonder that the Churches are half empty. Fancy suggesting that Great Britain, alone among the nations, should stop all forms of military preparation, scrap the Army, and disband the Air Fleet. Really, if one did not know you to be simply a respectable noodle, one might almost suspect you of active treason, to the Empire. To Heaven's sake, leave polities alone, and stick to your "Cure of souls."

October 1928. JOHN BLUNT.

---

DR. CAULCRICK'S CASE AND A MORAL.

*(From West Africa 6/10/28.)*

In its same issue "Truth" refers to the Caulcrick case, at Lagos, and the fact that the doctor found himself automatically stripped of his membership of the Legislative Council because of being fined for a purely political offence. "Truth" remarks that Governments nearer home may well sigh for such an easy way of getting rid of Opposition—"only as every sensible person knows, the effect of such laws is to drive opposition underground."

Upon which one would venture to ask why should Government of Nigeria even wish to get rid of Opposition parties in view of the swingeing official majority which is rung in automatically? On the other hand, how can the unofficial members in West Africa as a whole ever expect from Governments anything but what they get, until they begin to learn their business? Will it be believed that the Unofficial members in Nigeria never even meet for consultation and united action! And apparently it is the same in the other Colonies. So long as Governments have Oppossitions of that sort to deal with they would be more or less than human if they did not practically ignore them. The first thing "unofficials" must do if they wish to achieve anything is to act together.

---

DR SAP RA, I.S.O.

Dr. O. Sapara, I.S.O., wh[illegible] Abeokuta on the 6th October, 19 , on a trip, arrived Lagos on Tuesday, the 30th instant. Ẹ ku abọ, ọhun o dun bi?

---

MR. BAGAN BENJAMIN.

Town Councillor J. Bagan Benjamin, C.E., A.M.I.C.E., left Lagos for Epe on Monday, the 29th October, 1928, on Professional Engagement.

KING'S COLLEGE, LAGOS.

The King's College will re-open on Monday next, the 5th November, 1928, after three months' vacation.

We hope all the present Boys of the College will be punctual.

OLUṢAKIN.

---

O ṢE! ARAKUNRIN MI!!

Omije anu bọ loju wa pẹrẹpẹrẹ ni *Monday* ọsẹ yi ti a gbọ wipe ọdọmokunrin ti o njẹ Ayọ Alatiṣe, ti o nṣiṣẹ ni ṣọbu aṣọ awọn oyinbo Lagos Stores ni Ẹhingbẹti jalaisi. Ọdọmọkunrin yi kun fun ireti pupọ, o si jẹ enia ti ki iṣe apọn. Ṣugbọn orun rẹ wọ ni ọsan gangan ọjọ aiye rẹ. Igida.

A ki iya rẹ arugbo ti o fi silẹ lọ ati ẹgbọn rẹ pẹlu gbogbo awọn ẹbi rẹ pe nwọn ku ajalu na, Oluwa yio tu nyin ninu o. A si ki Mr. Ladega, ọga rẹ ni ibi iṣẹ pẹlu o ku afẹku.

Njẹ Ọgbẹni Ayọ Alatiṣe, o digbere, o dirinnako, o doju ala, o d' ọjọ ajinde.

Ki Ọlorun ki o dẹ'lẹ fun ọ.

---

IROHIN LATI BA WA TUN ILẸ IJẸBU-ODE ATI ILẸ RẸMỌ ṢE NI ỌNA RERE.

Mo juba o ẹnyin Alagba,

Ọrọ ti Ọba wa agba Ọlọla Akarigbo sọ sinu *Daily Times* 24-10-28, ṣugbọn mo rope o yẹ ki awọn ọba ẹhin rẹ ri si, o dara pupọ bi ọba wa agba ti sọ yẹn bẹni ni kutukutu ohun to wa po a nbọ lati sọ yẹn, ṣugbọn No. 1 a fẹ ki awọn agbagba jọwọ ba wa be awọn Ijọba Gẹsi ninu ọla nyin ki nwọn jọwọ jẹki awọn Lọya ma wa si Shagamu gẹgẹ bi ti Abẹokuta, yio dun mọ wa ninu bi awọn Lọya ba nde Shagamu aiye ilẹ Rẹmọ yio dara jubẹlọ.

No. 2 Nigbat a ba ri ọba ti o ba ru ofin tabi lu ofin, ko yẹ ki a sọ wipe ki awọn ọba tabi Ijoye ẹgbẹ rẹ ṣe idajọ fun rara bi o ba dun mọ on ninu ko ni dun mọ awọn ara ilu rẹ ninu gẹgẹ bi emi ti ro nitori na bi oyinbo bi ko ba ju ọmọ ọdun mẹjọ on ni o yẹ ki o ṣe idajọ irubẹ larin enia dudu tabi ni ilẹ enia dudu bibẹkọ awọn ti wọn fi ọba jẹ ni Ijebu-ode ati awọn ti o fi ọba jẹ ni Ijẹbu Rẹmọ tabi ti awọn oyinbo npe ni Lords ni wọn le ṣe idajọ awọn arufin, Ijoye Ọba ni yẹn ti ko ni fi si nkan yẹn o gẹgẹbi emi ti ro ni o. Ṣugbọn nisisiyi ohun ti mo ro pe o mu rukerudo yi wa si ile aiye ni ekini—wọn ko tun gba ọrọ awọn agba gbọ mọ, ekeji—wọn ko tun gba ọrọ awọn ọlọgbọn gbọ mọ, ẹkẹta—ọrọ awọn oiowo nikanṣoṣo ni wọn ngba gbọ nisisiyi, bẹni owe awọn

agba kan wipe itiju wọ ni li ọrun ju ẹru lọ, o da ifa fun Agbigbo ni ọjọ ti o ran ana rẹ ni ẹru, agbigbo gbọ ẹbọ ko ru ẹbọ rara, bẹni o di ijọ kan ti agbigbo ti oko mbọ ti o ri ana rẹ ni orere ile ti o ru ẹru ti ogun nkan ni ara rẹ, ibẹ ni agbigbo sọ pe ki ana on gbe ẹru wa, bẹ lo ran ana rẹ ni ẹru lo de ile rẹ, ibẹ ni wọn so pe ki nwọn sọ ẹru ni ori agbigbo ti ko ṣe sọ rara, ni a ti ojo na ni agbigbo ti di ero oko titi di oni. Ki Ọlọrun ma jẹ ki a ri ọran itiju larin wa. Amin.

Emi ni tiyin nitotọ,
J. A. O. SHOMADE.

---

## ỌLỌLA LỌYA DUHATI.

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*
Mo bẹrẹ f'oji,

Ni ọsẹ tokọja ni a ba awọn Ọlọla wa titun mẹtẹta sọrọ gẹgẹbi Aşoju-ilu nipa riran ti ilu ran wọn lọ si Igbimọ-Aşofin latari ọran ilu tabi fun rere ilu.

A si ni lati ma dupẹ lọwọ Ijọba fun anfani ribiribi ti nwọn fun ilu yi, eyiyi ni fifun ti nwọn fun ilu yi ni irufe anfani tamu-tamu yi lati ọdun karun, şugbọn ohun ti o tun şẹku lori eyi ni wipe boya bi o ba tun pẹ si Ijọba tun le ta ilu lọrẹ lati tun jẹki ilu ni·awọn Aşoju wọn ju ẹyọ mẹta pere na lọ.

Wayi o ọrọ ti Ọlọla Lọya Duhati ni a fẹ sọ loni niwọn-tun-wonsi, nitori e ọran tirẹ jẹ iyatọ larin awọn ẹgbọn rẹ meji iyoku (Ọlọla Jones ati Moore) fun kini; alẹ o ni Ọlọla Lọya Duhati jẹ nisis yi nipa Aşoju-ilu yi nitoripe ko de Igbimọ Aşofin sọrọ ri, boya o le ma lọ fi eti kọ ohun ti nwọn nsọ nibẹ ri a ko mọ, bi eyi ko tile jẹ bẹ, ki yio şai ma gbọ ohun ti nwọn nşe ni Igbimọ-Aşofin.

Lọna keji ẹwẹ, gbogbo wa ko şai mọ iru akatakiti ti o wa larin ẹgbẹ Dẹmọ latari Lọya Duhati nigbati nwọn fi nwewe li nwọn o ti yan Aşofin titun mẹta na, titi fi di igba ti ibo ilu fi mu u, ti ori ahun fi wọ igba nipa awọn ẹlomiran ti ko ni aniyan pe ki ilu yan an ninu.

Ọlọla Lọya Duhati na si sọrọ Ọmọluwabi gẹgẹbi o ti jẹ amudiju—o ni nigbati nwọn fi daruko on sinu awọn mẹta ti ilu nfẹ, eyiti a kọ sinu iwe yi loni, o si dupẹ fun gbogbo Jauma ti nwọn ko si fi oju omọde tnrin on nigbati on ke si wọn wipe on fẹ jẹ alaru ilu ki nwọn di ẹru ilu ru on na pẹlu, ti ilu si fi hẹn ti nwọn si şika alukawani wọn.

Ohun ti a fẹ ba Ọlọla Lọya Duhati sọ loni ni wipe, a gbọ wipe o ke si awọn ilu wipe on fẹ şe alaru ilu, on si ni oşuka ti o dara lọwọ ki ilu gbe ẹru ilu ka on lori, ologbo pa'mi-pa'mi o wọ o wa, awọn agbalagba lo ma npa Owe kan nwọn ni ileri ko to amuşẹ, ẹniti o ba şe ileri ti o ba mu şẹ ni Ọlọrun nfẹ, a wa si ti mọ wipe Ọlọrun nikan lo nşe ileri lo nmuşẹ On ko dabi ti awa ọmọ Anabi Adamọ ti a ma leri leka lasan, o yẹ ki a mọ wipe alukawani-kaaya ẹru Ọlọrun ni, ẹniti o ba şe ore fun loni ti o dupẹ, dajudaju ko ni si wohin-wọhun kan lati tun şe omiran fun oluwarẹ Owe ni o, ọna pupọ ni a ngba dupẹ.

Nitotọ ọdọmọde ni ọ ni arin awọn Aşoju rẹ meji iyokn ohun ekini ti o mu wa pe wọn ni ẹgbọn rẹ ni wipe nwọn şiwaju rẹ nigbati ilu dibo, ekeji ẹwẹ, ni wipe nwọn si tun şiwaju rẹ de Igbimọ na, a ko sọ ti Igbimọ Munisiba o, nitoripe o ti Kewu tibẹ ja, ki o şe Wolimọ lo ku, eyiyi ni wipe nigbati o ba tun di igba miran ti ọjọ ba pe ki ilu tun mura lati yan ọ sibẹ.

Nitorina ki o mura giri ki o tẹ şokoto bọ lati dide daradara si idi işẹ ti ilu gbe ka o lọwọ nigbakugba ti o ba kan, ki iwo ati awọn ẹgbọn rẹ meji iyoku ki ẹ mura nyin girigiri kẹ jumọ ma fi ero lu ero pọ, o ti di ijo ajumọ-jo ni iyẹn, nipa bayi ni nkan fi ngun gerege lai ni ikọsẹ ki ikọsẹ kan ninu.

"Ẹniti o ba mọ işẹ jẹ
Yio ma jẹ ojişẹ
Ẹniti ko si mọ işẹ jẹ.
Dajudaju yio ma jẹ okọşẹ!!!"

Iyẹn ki işẹ ohun ti o lọ titi larin awọn awọn Ọmọ Anabi Adamọ—Nitorina a toro fun nyin ki Oluwa ma jẹ a ri dasi, ki ajinde-ara si ma jẹ nyin o—Amin.

## Ẹ KU ILU WA YI ATI KINI ILU WA YI TI NLỌ SI?

Ede meji yi jẹ ede ti ogunlọgọ enia ma nlo ti ẹni meji tabi mẹta ba pade arawọn lode.

Kini nwọn ti ma nwi ani ti nwọn ba pade arawọn? Ekini a dahun ti nwọn ba jẹ wipe nwọn ma mba arawọn jẹwọ tẹlẹtẹlẹ ti nwọn ba si jumọ wa ninu jauma kanna pe "Ẹ ku ilu wa yi, ati kini ilu wa yi ti nlọ si?"—Ẹnikeji yio dahun wipe bi ilu na ti nlọ si ko ye awọn yio si tun ma pada bi ẹnikeji rẹ wipe ewo ni ẹ gbọ?

Eyiti o si kọkọ kọ si ẹnikeji rẹ wipe "Ẹ ku ilu wa yi. Ati kini ilu wa yi ti nlọ si?"—Yio ma fi esi tun eyiti o tun mbebi pada wipe awọn ko gbọ ohunkohun bi gbogbo rẹ ti nlọ si, nitoripe bayi ni awọn gbọ wipe kini kan fẹ şe, awọn ko si gbọ nkankan nipa rẹ mọ, bi nwọn ba wo titi ti nwọn ko ba mọ eyiti nwọn ma şe, nwọn a gbe irọ kẹnkẹ-kẹnkẹ nla kan ju silẹ pẹ larin arawọn, bokenran ki nwọn sin dide tutu ti nwọn ju fun arawọn si arin arawọn nọ? Nnwọn r ma wa gbe lankẹ rẹ kiri gbogbo adugbo ki adugbo ti

nwọn ba de, titi iyẹn ma fi bu ka'lu, ti gbogbo rẹ yio si ma ṣe iogbodiyan, bi Jimọ ku ọla.

Nigbati nwọn mbi arawọn lere ni iduro pe "Ẹ ku ilu wa yi, ati kini ilu wa yi ti nlọ si?" Ki nwọn ma ṣe alai ri labari irọ kan gbe ju silẹ lati fi tun arawọn ṣe pe awọn ngbọ bi nkan ti nlọ si larin ilu.

Eyiti o pade ekeji rẹ lọna, ti o mbebi lọwọ rẹ bi ilu ti nlọ si, ti o si tun nki pe ki o pẹlẹ o nipa ọran ilu, o nfẹ gbọ labari kan ni iyẹn, iwọ ti nwọn si bi lere pe kini ilu ti nlọ si lẹhin igba ti oluwarẹ ki işe aşọde, otitọ ti dara julọ lati sọ fun ẹniti o fi wa oluwarẹ lẹnu.

Esi ti o yẹ ti a ba fi ie irufẹ awọn ibere bẹ ni wipe :—

"Ọlọrun jẹki o dara
Ọlọrun jẹ o toro
Ọlọrun jẹki o rọju
Ọlọrun ko fi alafia to ilu
Ọlọrun ko pana omi-rikişi
Tabi omi-tẹmbẹlẹku."

Bi a ba fi iru awọn adura baun fi ṣe esi, o kuku san julọ lati ma sọ ohun ti oju ẹni ko to, irufẹ awọn isọkusọ tabi irọ ti awọn aturọta ma npa kiri ki işe ohun ti o le ma tun nkan ṣe bikoşe lati ma ba nkan jẹ.

Ngo la oye kan fun nyin nipa eyiti mo wi nisisiyi lati fi ṣe akawe.

Agbole kan wa, awọn enia ti o mbẹ ninu agbole na pọ, nigbati o ya, Aşitani tẹsẹ bọ arin wọn, nwọn ko rikişi bọ arin arawọn, nwọn da si ọna meji, awọn apakan a dide nwọn a ro irọ kan nwọn a pọ si ẹnu apakan lati ma gbe lankẹ rẹ kiri, ti awọn apakan ba si nta kayiti irọ iyẹn kiri awọn eyiti o gbe irọ na ju silẹ pẹ nwọn a ṣe şin bi ọbẹ pan, nibiti awọn apa keji gbe nta kayiti irọ na kiri a dogun ohun ti Meigida-agbole na ngbọ, awọn apakan ti ro irọ yẹn fun arawọn, nwọn a tun dide lọ si ọdọ Meigida-agbole na wipe bayi-bayi ni ọrọ ti awọn arabi nsọ kiri, mo bi nyin kini ẹ ro wipe yio ti ri?

Nigbati ọran ba delẹ bayi olukuluku ni lati ma sọ mutuşi ẹnu rẹ nipa a ti ma gbe lankẹ ohun ti ko ṣe kiri bi ẹni nfi ọwọ ara ẹni şişẹ ti a si nfi ẹsẹ ara ẹni yi danu lo jẹ loju wa.

Ọpọlọpọ irọ lo nba kan jẹ a ni a nfẹ ki ilu dara, ni awọn apakan nja fun, awọn apa keji na si le ma a fun ki ilu dara lọkan wọn, şugbọn Ọlọrun nwo igba-aiya olukuluku, ọkan da wa loju pe ẹniti o ba ja ilẹ ilu yi, ilẹ na yio bere lọwọ rẹ dandan bi o ti du ki o pẹ to, iyẹn ki işe ọran epe rara.

Nitorina gbogbo ẹnyin ti ẹ mba nsaba ki ara nyin pe ẹ ku ilu wa yi, ẹ fi mọ lori iyẹn, nigbati o ba şẹ tun ndi ogun wipe a mbi ara ẹni lode pe kini ilu wa ti nlọ si yi, irọ nfẹ de ibẹ ni iyẹn, ti ẹ ba fẹ mọ bi ọran ilu ti nlọ si, ti ẹgbẹ ilu ba nşe pade ki ma lọ gbọ ohun ti nwọn nsọ nibẹ.

Ki işe ọtẹ ni nwọn o ma di nibẹ, bẹ ki işe irọ ni nwọn o ma pa fun arawọn nibẹ bi nkan ti nlọ si ni nwọn o ma fihan arawọn ati ni ọna ti nkan yio fi dara nilu.

Bi bẹkọ ẹ ma lọ si ọdọ awọn sugaba nyin lati ma lọ bere bi ilu nyin ti nlọ si, iyẹn ti o ba jẹ wipe ẹ nfẹ ki nkan dara gẹgẹ bi itara ẹlomiran.

A tọrọ adura, ki Ọlọrun fi aiya ilu balẹ, ki işẹ wa, ki owo wa, ki alafia wa, ki ọmọ wa, oluborí ẹ ki Ọlọrun sioki aluba o de yi fun ilu—Amin

Emi ni ti nyin nitotọ,
KEKERE-AWO.

---

## IROHIN ẸDẸ.

### NAWO-NAWO O KUNAWO ỌMỌ A YE Ọ.

Ọrọ oke yi lo bọ l' ẹnu l' ọjọ ọsẹ tokọja yi, 28-10-28, nigbati tọkunrin tobinrin pesẹ si ile Ọgbẹni Joseph Adeniran ni agogo mẹwa abọ ọsan fun iko-ọmọjade ti iyawo rẹ bi ni ọjọ *Sunday* to kọja yi. Ka to şẹjupẹ orişirişi awo onjẹ bẹrẹ si jade lati ọdọ awọn iyalaese to tinu iyalase wa, bẹni nkan mimu pẹlu. Orişirişi awọn ẹgbẹ to wa sibi ere na to Ẹgbẹ mẹwa bi Ẹgbẹ Imale ti nwo, bẹni Ẹgbẹ Onigbagbọ bẹ si ni Ẹgbẹ alaigbagbọ pelu. A! inawo ọjọ na pọ ki Oluwa da ọmọ na si o, amin.

Awọn ti wọn si wa gẹgẹ bi ọrẹ to igba enia (200 people.) Olukuluku bẹrẹ si daşeri fun ẹnyin tanpẹpẹ ẹlomiran iyan ati amọla o si bẹ si bu obi bi eso lapalapa; nitori emi nikan gba to ogoji ọbi Njẹ a ki ẹnyin Ẹgbẹ Kilıẹ ku abaşe ti akọwe nyin o. Giwa Lawani Adeigbe, Balogun Lawani Ajala, Sarumo Lawani Akanni, ati awọn şaraki-şaraki yoku ẹgbẹ ko ni bajẹ o, amin, ire a kari gbogbo wa o. Ọmọ na a tula o, amin.

---

### ORI IV.

## IṢẸ.

(*Translated from "Character by Dr. Smiles"*).

APA OGUN.

Sibẹ, ọpọlọpọ ni awọn ti o ni ẹkọ ijinlẹ ti o si jẹ onişẹ gidi. A ko gbọ pe Sir Isaac Newton kuna ninu işẹ Ọga ile ti a nrọ owo, nitori o ni ẹkọ ijinlẹ. Bẹna si ni a ko gbọ pe nwọn ri ohunkohun sọ si

Sir John Herschel lara nigbati o nṣe iṣe kanna.

Awọn Humboldt tẹgbọn-taburo bakanna ni nwọn jẹ omu ninu iṣẹ-kiṣẹ ti nwọn dawọ le—bi ti iṣẹ iwe ni, bi ti ẹkọ ijinlẹ ni, bi ti wiwa ohun iṣura ti nbẹ ninu ile ni, bi ti ẹkọ ijinlẹ ede ni tabi niti iṣẹ oṣelu.

Niebuhr, Opitan, jẹ oṣiṣẹ tara. O ṣiṣẹ *Secretary* ati *Accountant* fun *African Consulate*, (ipc ti awọn Ijọba ilu Dane yan si) daradara tobẹ ti nwọn tun fi jẹ ọkan, Olotu owo ilu; nigbati o si fi iṣẹ yi silẹ, o gba iṣẹ Olotu ile ti a nfi owo pamọ si ni Berlin. Ninu pe o nṣe iṣẹ wonyi ni o waye ti o si kọ itan Rome, ni o kọ Arabic, Russian ati awọn ede Scalves miran, ni o si wa di ẹniti gbogbo enia mẹ ni Ọga ninu iṣẹ iwe ṣiṣe eyiti a fi ndarukọ rẹ ju loni.

Niti eyiti Napoleon Ekini sọ nipa, awọn ti o ni ẹkọ ijinlẹ, a ba ni ero pe on na iba ṣagbara ki o fa nwọn mọra ki nwọn ba tun ilu rẹ ṣe. Awọn miran ti o gbe si ipo, okitutu ni wọn, awọn miran si pe pere-pere. Bayi ni a ri i pe o gbe Laplace si ipo *Minister of Interior*; ṣugbọn kete ti o de ipo yi ni o ri i pe ko to tun ipo na. Lẹhin eyi ni Napoleon sọ nipa rẹ, pe "Laplace ko gbọn to. Bi ọrọ delẹ a ma tọpinpin; bi yio sin ṣe nkan, a ṣẹṣẹ joko silẹ ro o titi lọ na. Ṣugbọn iwa yi ti mọ Laplace lara ninu iṣẹ ẹkọ ijinlẹ ti o kọ, ko si le yipada nigbati o kan ti iṣẹ miran.

Ti Daru yatọ. Ṣugbọn Daru jẹ anfani ti pe on ti ṣiṣẹ gidi ri, o ti ṣe iṣẹ alabojuto awọn ọmọ-ogun labẹ Massena ni Switzerlan nigbana ni o si ṣe iwe. Nigbati Napoleon ni on yio fi jẹ igbimọ ilu ati alabojuto Ile Ọba, Daru ko fẹ. O ni, "Ti iwe ni mo fẹrẹ fi gbogbo ọjọ aiye mi gbọ, emi ko si ri aye lati kọ iṣẹ amẹwa." Napoleon dahun o ni, "Niti amẹwa, mo ni wọn o pọ; nwọn mọ iṣẹ wọn. Ṣugbọn mo nfẹ enia ti o ni mimọ, ti ko dẹ, ti ko si fara silẹ; nitori o jẹ ẹni bẹ ni mo ṣe yan ọ."

Daru jẹ ọhẹn, o gba eyiti Ọba wi, o si wa di olori gbogbo awọn Amẹwa Ọba, o ṣe iṣẹ na pebe, bẹni iwa rẹ ko pada, bakanna ni o nṣe jẹjẹ ti o nhuwa ọmọlawabi ni gbogbo ọjọ aiye rẹ.

Iṣẹ ti di ara fun awọn enia ti o ba ti fi iṣẹ ṣiṣe kọra, tobẹ ti nwọn a korira ọlẹ tabi oraye: bi ohunkan ba si de ba wọn ti nwọn ko le ṣe iṣẹ ti nwọn ti kọ mọ, nwọn a wa iṣẹ miran ṣe. Oṣiṣẹ enia a wa nkan ṣe nigbati o ba ṣiwọ iṣẹ ti ọwọ rẹ ba dilẹ, on a si ri isimi nibiti ọlẹ enia ko ri i. George Herbert ni, "Ẹniti ko lo akoko isimi ko ni isimi." Bacon ni, "Ẹniti o ba jẹ oṣiṣẹ tara tabi gboke-gbodo enia, ninu pe iṣẹ fẹrẹ diẹ ṣugbọn o nya bọ, ọpọlọpọ asiko isimi ni o ni, ayaṣebi oluwarẹ ba jẹ enia ti o lọra tabi ti o lọ dawọ le iṣẹ ti o ju lọ, eyiti iba fi silẹ fun awọn ẹlomiran lati ṣe." Nitorina ni a ṣe ri i, pe ọpọlọpọ nkan nla ni enia ti ṣe, ninu igba ti iṣẹ fẹrẹ nilẹ, awọn enia ti iṣẹ ṣiṣe ti di ara fun, ti o si ya lara ki nwọn ṣiṣẹ ju ki nwọn ṣe ọlẹ lọ.

Ani awọn iṣẹ ti enia gbadun ni ṣiṣe lati fi daraya, ma nkọ ni lọgbọn iṣẹ. Eyi a ba ni wa nkan ṣe, o kere ju, a funni ni iṣẹ ti o ba ara mu ṣe. Ki iṣe bi ti Domitian ti o npa eṣinṣin ni a nwi. A tilẹ gbọ ti Ọba Macedon ti o nṣe atupa ati ti Ọba Franse ti o nṣe aṣigbe. Ani awọn iṣẹ ti a nfi ọwọ pa lojojumọ dara fun enia nigbati iṣẹ ba wọn lọrun eyi a jẹ isimi.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

---


## KERE O!

Mr. C. B. SHODIYA, *Produce Buyer*, ti No. 132, nitosi Niger Company, Ebute Ero, ni ọpọlọpọ Tapo (Tapaulin) siye 15 x 15 fun hihaya, bi o fẹ ṣe ariya ti Iyawo lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe Wolimọ lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe ariya nipa ti oku lọ sibẹ, o wa fun ẹnikẹni ọpọku-ọyọku ni owo hihaya rẹ.

9d. ẹgbẹdogun fun Tapo kan lojumọ.

C. B. SHODIYA,
*Produce Buyer*.
132, Ebute Ero,
Marina, Lagos.

## *Use Yaro for your baby!*

All experienced mothers give testimony in praise of "Yaro" as an indispensable 'Preservative' for 'Babies' Yaro has no equal in suppressing those complaints which make infants feel uneasy, especially during their critical teething period. Trust Yaro for all infants' complaints and use it for your baby. Price per bottle 3/3d.& 2/3d.

## *Increased health for 3/- only.*

"Life Tonic Tablet" imparts tone and vigour to the body, renews every atom of the flesh, prevents brain fatigue and brings indescribable comfort to all mental workers.

Price 3/- per bottle.

## *A chance for female sufferers.*

Wireless Female Pills, the latest Scientific Discovery, have answered divers cases of functional complaints of disorders peculiar to women. These Pills serve as an effective fertiliser against barreness Give "Wireless Female Pills" a trial and prove its reliability.

Our Anti-Plague Disinfectant Fluid kills dangerous flies, bugs, cockroaches, etc., etc. 1/- and 1/6d per bottle.

### *Anti-Gon Pills.*

Get rid of veneareal diseases before they get rid of you by using Anti-Gon Pills--a reliable antisceptic against Gonorhea. 3/- per bottle.

WE ALSO STOCK:—

Glaxo (large and small sizes)
Vitafer—Brain Tonic
Walk Easy Anti-Rheumatic Salt 3/6 & 2/-
Pile Pills 1/6
Vibrona Wine 7/6
Lactogen
Kalzana
Effective Pile Remedy 7/6
Back and Kidney Pills 2/-
Zotal 1/6 & 2/6

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office:*—88, Broad Street, Lagos,
*Branches:*—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
109, Griffith Street, Ebute Metta.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

### AREMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:— Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILN ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

# TO LET.

## One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to —

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

# ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

———:o:———

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.